PRIORITY
PAR AVION
BY AIR MAIL




# Lẹta kan fún ọ

**ISBN 978-3-98824-165-8**

© 2024 by GBV Dillenburg GmbH
www.gbv-dillenburg.de

Inurere ti
Verbreitung der Heiligen Schrift, www.vdhs.com

Bíbélì Mimọ ti a lò jẹ eyiti a tẹ lati-Internatioal Bible Association, Dallas. 75222

Atunkọ sí èdè Yorùbá lati ọwọ -: David S. Omojola, echoes _of_truth@yahoo.com, +234 8033064183

Printed in Nigeria

© photos: p. 11 l.: Daniel Ernst, stock.adobe.com; p. 11 r.: Diversity Studio, stock.adobe.com; p. 46: Renate Wefers, stock.adobe.com; others: panthermedia.net, et al.



# Si iwọ Bi Ẹnikan

Lẹta tí ó mú lọwọ yi ṣe pàtàkì pupọ eyiti o sì wa fún ọ bí ẹnìkan.

O lè ro wipe: “Ṣe lẹta kíkọ si inu ìwé kò ti máa di nkan àtijọ́” ? Otitọ ni. Lẹta ti ndi ohun tí a nfi atẹjiṣẹ ati ìwé ẹrọ alátagbà rọpo.

**>> Ṣùgbọ́n pẹlu aiye ẹ̀rọ ìgbàlódé, ohun tí ó ṣì jẹ ìtẹ́wọ́gbà ni lati kọ lẹ́tà pàtàkì sì inú ìwé láti lè fi iyebiye ati pàtàkì wọn hàn.**

O lè ṣàkíyèsí, fún àpẹrẹ, kí ó gba ìwé ipe láti orí ẹ̀rọ ìgbàlódé sì ibi igbeyawo ẹbí ọba!

Jọwọ́  wa aye fun lẹta pàtàkì tí ìwọ mú lọwọ ni.
O ṣé pàtàkì pupọ. Nitorina fi ara balẹ kaa. Iwọ kí yio si kabamọ rẹ!

**Ìwọ yio ri ọ̀rọ̀ iyanilẹnu  nípa**

- **> lẹta miran, tí ó tún ṣe iyebíye julọ**
- **> ọrọ akọsilẹ tí ó ni ìtumọ̀ ju ni aiye**
- **> ọrọ ti o ga julọ ni igba gbogbo ati ni jíjẹ ojúlówó tí ó sì wúlò fún òní.**



**Lẹta iyebíye julọ yi , Bíbélì, Jẹ ọrọ fún ọ gẹgẹbi ẹnikan, tààrà láti ọ̀dọ̀ Ọlọrun.**



**>>> Iwọ yio jèrè ibukun nla nínú rè Bí ìwọ ba ṣii tí ó sì kaa.**



# Bíbélì Mimọ - Lẹta kan fun ọ

## Bíbélì dabi iwe iranṣẹ afẹfẹ – Ọrun ni ipinlẹṣẹ rẹ.

**Ọlọ́run ni Ẹlẹda iyanu agbaiye.**

**Oun naa ni O fún ọ ní iye, O sì mọ ọ Pátápátá. Iwọ kí nṣe ẹniti o ṣèèṣì wa!**

**Òun nwa ibaṣepọ pẹlu rẹ, O sì nṣe Iṣipẹ ifẹ Pẹ̀lú rẹ nipasẹ 'lẹta' Rẹ.**

Ìwọ kò ha tí mọ lẹta Ọlọ́run sibẹ? Bóyá ó tilẹ̀  Wa ni ibikan nínú ilé rẹ, l'aika.

Ìwọ kò jẹ fi aibìkítà ju lẹta tìrẹ sì ibikan bẹẹ. Iwọ yio ka pẹlu ifarabalẹ. Nitorina, sí lẹta Ọlọ́run sì ọ - ka Bíbélì mimọ!

Iwọ kò ha ni Bíbélì bi?, gbiyanju lati ni eyiti iwọ yíò máa ka, yíò sí ṣe ọ ni anfani pupọ̀.



# Lẹta Araọtọ

Bẹẹ ni, ó ti ye ọ daadaa: Bíbélì mimọ, Ọrọ Ọlọrun ni a nsọ nihin, eyiti àkòrí lẹta kan sì ọ bamu dáadáa. Ìdí rẹ tí lẹta Araọtọ fi ṣe pàtàkì ni wipe, tí Ọlọ́run ní.

O lè jiyàn: "Ṣùgbọ́n ní nkan bi ọgọrọrun ọdún pupọ sẹhin ni bíi ogójì ènìyàn kọ Bíbélì. Tí a kò tilẹ nda orúkọ nwọn."

**Bẹẹni, otitọ ni. Sibẹ Ọlọ́run sọ ọrọ Rẹ tààrà fun ẹnia kañkan:**



**Nítorí àsọtẹ́lẹ̀ kan ko ti ipa ifẹ enia wa ri; Ṣùgbọ́n àwọn enia ńsọrọ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run bí a ti ndari wọn láti ọwọ Ẹmi Mimọ wa.**

Peteru kejì 1 :21

Ọlọ́run lo ẹ̀bùn nwọn, ìwé kika nwọn, àṣà iṣẹmbaiye nwọn, Imọ ìgbàlódé àti ọna ìwé kíkọ nwọn.
*>>> Nwọn kọ ọrọ ti Ọlọ́run fẹ ki nwọn kọ gañ.*
Eyi ni a npe ni "imisi".

## Àwọn Ìwé inu Bíbélì

> Bíbélì pin sì ipa meji:

- > Májẹ̀mú Laelae (ìwé mọkandinlogoji)
- > Májẹ̀mú Títún (ìwé mẹtadinlọgbọn)

> Májẹ̀mú Tititun ni :

- > ìwé ihinrere mẹrin
- > ìṣe Àwọn Aposteli
- > Lẹta episteli mọ́kànlélógún
- > Ìfihàn

Bíbélì fún ọ ní ìdáhùn sí ìbéèrè ìgbé aiye.

Nípa kika rẹ, ìwọ ni anfaani lati ri àyípadà sì daadaa tí ifẹ Ọlọrun lè mú wá sí aiye rẹ.

Jẹnẹsisi
Ekisodu
Léfítíkù
Numeri
Diutaronomi
Jọṣua
Àwọn Onidajọ
Rutu
Samuẹli kini
Samuẹli keji
Àwọn Ọba kíni
Àwọn Ọba Keji
Kronika kíní
Kronika keji
Ẹsira
Nẹhimaya
Ẹsiteri
Jobu
Orin Dafidi
Iwe Owe
Iwe Oníwàásù
Orin Solomoni
Aisaya
Jẹrimaya
Ẹkun Jẹrimaya
Ìsíkíẹli
Daniẹli
Hosia
Joẹli
Amosi
Ọbadaya
Jona
Mika
Nahumu
Habakuku
Sefanaya
Hagai
Sakaraya
Malaki

Matiu
Maaku
Luku
Johanu
Ìṣe Àwọn Aposteli
Romu
Kọrinti kini
Kọrinti keji
Galatia
Efesu
Filipi
Kolose
Tẹsalóníkà kini
Tẹsalóníkà keji
Timotiu kini
Timotiu keji
Titu
Filemoni
Heberu
Jakọbu
Pétérù kini
Peteru keji
Johanu kini
Johanu keji
Johanu kẹta
Juda
Ìfihàn



## “Ìran tí ó d’ori kọ isalẹ”

Njẹ ìwọ pẹ̀lú ha jẹ tì ìran yi bí, tàbí ọrọ yi ko ni ìtumọ̀ sì ọ? Njẹ nígbà gbogbo ní ìwọ má nd’ori Kọ isalẹ ni kikiyesi ẹ̀rọ fóònù tàbí tí palaba imulọwọ?

Ni wiwa ni ori ìlà alatagba nígbà gbogbo ati ni ibi gbogbo yio mu ki o ri sínú agbami irohin lati ori ìlà alatagba. Njẹ ohun miran tún wà lẹhin lílọ kiri lati ori ìlà ibanidọrẹ kan sì èkejì. Wakati pupọ yio lọ laifiyesi, ọpọlọ rẹ yio si kun fun onírúurú - láìsí àní-àní ọkan rẹ yíò di bajẹ. Ki nṣe èyí nikan, ṣùgbọ́n èyí yio di ọ lọwọ ni riro nípa Ọlọ́run àti ọrọ Rẹ si ọ.

**Àkíyèsí:** Bí ìwọ bá fẹ́ mọ Ọlọ́run bí ẹnìkan, ìwọ kò lè rekọja Bíbélì. O nílò idakẹjẹ ni àyíká rẹ láti kaa. Nitorina, panọ ohun gbogbo tí ó lè di ọ lọwọ. Yio ya ọ lẹnu bí èyí yio ṣe ṣe ọ ní rere. Ẹ̀ro rẹ yio yi pada si rere, ọ̀nà mimọ tí ìwọ kò ṣe abapade rẹ ri.

Nípa kika Bíbélì, ìwọ yio lè rí otitọ kí ó sì mọ ẹnikan tí ó ni inu didun sì ọ, tí ó fẹ́ràn rẹ, tí ó sì fẹ fún aiye rẹ ni ìtumọ̀ àti ilepa rere.

Ni oju ewe 62 & 63 ìwọ yio ri ọna ti o le gba ka Bíbélì.

**Jọ̀wọ́ lo o!**



# Njẹ Bíbélì sí kun ojú òṣùwọ̀n bi?

**Ọpọlọpọ eniyan gbagbọ pé ìwà aigbọn lati ni nkan ṣe pẹlu “iwe àtijọ́ ti ko ba ìgbà mu mọ.” Ipinnu ti nwọn ni wipe ènìyàn ìgbàlódé kò lè gbà Bíbélì gbọ mọ.**

**Àwọn ìrònú bayi ni onirohin má nti lẹhin ti a si ngba wọlé láìsí ìbéèrè.**

**Sibẹsibẹ, ọ jẹ ero aburú ti o w'ọ̀pọ̀ pè ẹnikẹni ti o ni ọpọlọ ati òye ni lati yago fún Bíbélì .**

**Ni awọn oju-ewe tí ó wà níwájú ìwọ yio ri awọn ẹ̀rí ifidimulẹ ìwúlò àti ìtumọ̀ Bíbélì.**

**Ibukun ni fun àwọn tí ngbọ ọrọ Ọlọrun, tí nwọn si paa mọ.**

Bíbélì – Luku 11 ẹsẹ 28

# Iyanu Ohun-elo Orin



Ọkan ninu awọn ọrẹ mi jẹ olorin, ti o si le lo pupọ ninu awọn ohun-elo. O nlo ẹ̀rọ kọmputa rẹ láti fi gba ohun orin silẹ, tí ó sì ti ipa ẹ̀yí po nwọn pọ.

O ṣé alaiye: "Lakọkọ mo mú ohun-elo kan fi kọ ohùn isalẹ. Ẹ̀yí dúró fún igba ohun silẹ àkọ́kọ́.

Ni igba ohùn silẹ kejì, mo lo ohùn òkè lai pa tí ìṣáájú rẹ. Bi mo ṣe lo ohun-elo mẹfa ni yi titi de eyiti o rinlẹ julọ.



Nigbati a kò ohun orin mejọ nwọnyi papọ, o ha fẹ mọ àbájáde rẹ?"

Ohun ti mo gbọ jẹ adùn orin ologo tí ó ṣòro láti gbagbọ pé ẹnikan lo wa ni ìdí rẹ.

Bẹẹ gẹ́gẹ́ ni Bíbélì tí ri, a kọ láti ọwọ àwọn enia tí ó lé ní ogóji. Gbogbo wọn ni a misi láti ọwọ Awamaridi na, Ọlọrun, Ẹmi Mimọ ti O mu ki "ohun-elo" ogóji nwọnyi ṣeré.

**Iwé Bíbélì kọ̀ọ̀kan ni ó ni ìwà-enia tí rẹ̀, ṣùgbọ́n gbogbo rẹ ṣíṣẹ papọ gẹgẹbi eto Ọlọ́run.**

**Eyi jẹ ọkan lára àgbà-yanu Bíbélì.**

**>>> Ká Bíbélì ni ṣisẹ ntẹle kí ó le ri ibaṣepọ araọtọ !**







# Duro Lasan

Ọkùnrin kan tí kò bìkítà rárá nípa Bíbélì, nfẹ yi ọ̀dọ̀ 'mọkunrin Kristẹni kan lọkan padà pé Bíbélì kò kun ojú òṣùwọ̀n, àti wipe ó lòdì sí àwárí òde òní. O wa fẹ fi àwọn akọsilẹ imọ aiye ati ìtàn asán tí enia nipa ọrọ yi ranṣẹ sii.

Igbagbọ ọmọkùnrin na ko mi rárá. O dáa lóhùn: "Bi iwọ bá ní ohun tí ó dára jù ìwàásù ori òkè. (Mátíù 5 - 7), ohunkóhun tó dùn gbọ ju ìtàn: Alaanu ara Samáríà, Ọmọ onínà kùnà, tàbí obìnrin ni ibi kànga sikari (Luku 10, ati 15; Jòhánù 4) Ti o ba ni ohun tí ó tú ni nínú ju Orin Dáfídì 23, tàbí mọ ohun kan tí ó fi ifẹ Ọlọrun han si mi ti o dara ju ẹ̀bùn Jesu Kristi Ọmọ Rẹ, tàbí ó lè fún mi ní ohun kan tí ó ṣe àpèjúwe àiyeraiye ọjọ iwaju daradara ju Bíbélì lọ: Jọ̀wọ́ fi ranṣẹ sì mi kíákíá!"

O duro lásán fún esi.

**Ko si ìwé tí a lè fi we Bíbélì. Ìdí rẹ ni wipe, ìwé Ọlọ́run ni Bíbélì.**

# Bi Bíbélì Ṣe Tọ wa wa

## Bawo ati l’ori kini awon eniyan kọ̀wé?

Ẹgberun kan ọdún ṣáájú Kristi

Bi ẹnikẹ́ni ba fẹ kọ “lẹ́tà” ni nkan bi ẹgbẹ̀rún marun ọdún sẹhin, ki nṣe iwe ati kalamu ni nwọn nlo. Ni ìjọ wọnnì, ohun tí nwọn nlo ni àmì tí a ha sì ara abala àmọ́, eyiti nwọn yio sa gbẹ tàbí sun.

Nigbati nwọn nha ilẹ̀ ni ilu nla ìgbàanì ni Síríà àti Iraki òde òní, Ẹgbẹgbẹ̀rún irú àwọn abala àmọ́ sisun tí a kọ ọrọ sì ni nwọn ri.







Ẹgberun kan àbọ̀ ọdún ṣáájú Kristi

Ni asiko kanna, ni àwọn ará Egipti ṣe agbe dìde ọna ìwé kíkọ miran. O gba àwọn onímọ̀ èdè ni ọgọrọrun ọdún lati le ri àwọn èdè àtijọ́ ẹda eniyan.

Àwọn ọna ìwé kíkọ wọ̀nyí ni àléébù. Nwọn ni ọgọrọrun àmì nínú wọn. Bí ẹgbẹ̀rún kan àbọ̀ ọdún kí a tó bí Jésù ni a to ni ọrọ A.b.d.

Ẹgberun mẹta ọdún ṣáájú Kristi

Pẹlu àyípadà diẹ, a.b.d gbilẹ kiakia lẹhin ẹẹdẹgbẹ̀ta ọdún, èyí ni ó jẹ́ ipinlẹ abd latini tí ó ṣì wà ní lilo titi di òní.



Yàtọ̀ sí àmọ́, òkúta,igi, àwọn enia tún nfi papiru, tí a mú jáde láti ara irúgbìn kọ we. Nigbọṣe, àwọn enia nkọ we sì ara (awọ ẹranko) èyí ni nwọn sọ di awọ kika.

**Bayi ni Ọlọ́run ṣe gba ọna iyanu pé nígbàna ti a fi kọ Bíbélì , ọna irọrun tí ìwé kíkọ fi lè ye enia tí wa.**

## Kíkọ, kikojọpọ àti títọju

Mose jẹ ọkan ninu awọn ẹni àkọ́kọ́ tí ó kọ Bíbélì. A ka ni ọpọ ìgbà wipe Ọlọ́run fún ni ojúṣe àti kọ àwọn ohun tí o ti ṣẹlẹ̀ sínú iwe.

Ọgọrun ọdún lẹhin iku

Nipasẹ awọn ti Ọlọ́run yàn, Nwọn ṣe àkójọ pọ Májẹ̀mú láéláé pẹlu itọju daradara.

Ni nkan bi irinwo ọdún ṣáájú Jesu Májẹ̀mú láéláé pari. Èdè Hébérù ni a fi kọ pẹlu diẹ ni Aramaiku.

Irinwo ọdún ṣáájú Kristi

Láti ìgbà iku ati ìgòkè re ọrun Jesu Kristi di ọgọ́rùn ọdún àkọ́kọ́ ni a kọ àwọn iwe Májẹ̀mú titun ni èdè giriki tí ó gbilẹ nígbà na.

Mósè ku ni nkan bi Egbèje ọdún ṣáájú Jesu, A lè sọ pé Bíbélì jáde laarin àkókò Ẹgbẹ̀rún kan àbọ̀ ọdún.

## Pipari ati idanuduro.

**Ni kiakia ni àwọn Kristẹni ìṣáájú mọ nípa ìtọ́ni Ẹmi Mimọ, ìwé wo ni ó wà pẹ̀lú Bíbélì ati eyiti ko sí. Nwọn ni àfiyèsí pàtàkì tí nwọn fi lè f'ọwọ si ìwé pé ó jẹ́ ojúlówó, (Bíbélì) àti eyiti kí nṣe ojúlówó (apokirifa).**

Matin Luda ķiyesi àwọn iwe apokirifa, wipe nwọn ko le wa ni ipo kanna pẹlu Ìwé Mímọ́. Ni kikaa ìwọ yio ri wipe àwọn ọrọ rẹ tako àwọn iwe Bíbélì.

Ìtàn lásán nípa Jesu àti àwọn Aposteli, ayédèrú lẹta láti ọwọ àwọn enia igba Bíbélì, ati awọn àṣìṣe itan agbegbe ni nwọn kun inu rẹ. Ni ọdún 1545, ní ìpàdé Tirenti, àwọn iwe wọnnì ni nwọn fi idimọlu fi sì ipò kanna pẹlu Ìwé Bíbélì, kí nwọn le fi idi àwọn ẹ̀kọ́ odi múlẹ̀. Gbogbo èyí fi hàn gbangba pé Apokirifa ko ni imisi. Ìdí ni yi ti o fi ni lati ka Bíbélì tí kò ní ìwé Apokirifa.

**Ọrọ Ọlọrun wa lara awon oniruru ìwé tí a fi arabalẹ ko jọ pọ nípa ìtọ́ni Ẹmi Mimọ, O si ti pé lati ìgbà náà.**

**Bíbélì ni a pè bí o ṣe tọ ni Ìwé Mimọ, nitori ó wá lati ọdọ Ọlọrun, kí nṣe nípa àṣẹ enia. Loni òun ni àṣẹ tí ó ga julọ fún igbagbọ àti aiye wa.**

> **Ọrun ati aiye yio kọja lọ, ṣùgbọ́n ọrọ Mi kì yio kọja lọ bi o ti wú ki o rí.**
>
> Bibeli – Mátíù 24 ẹsẹ 35

## Akọsilẹ to kúnjú òṣùwọ̀n

Akọsilẹ tí ó ju bí ẹgbẹ̀rún marun pẹlu awọn itọkasi Májẹ̀mú Títún ni èdè giriki tí wa ni itọju. Eyiti o gbajumọ julọ ni Kodẹsi Sinatiku, èyítí ó sì fẹrẹ jẹ Bíbélì giriki ni Ipamọ julọ. Láti bí saa ọọdunrun ọdún tí ọmọwé kọstantan Tiṣendọfu ni ibi ikẹkọ Katirini mimọ ni Erekusu Sinai ni 1859. Ohun elo iyebíye yi ko wa nínú Májẹ̀mú laelae nikan ṣùgbọ́n ninu iwe mẹtadinlọgbọn Májẹ̀mú títún pẹlu.



Ni àwọn ile ìsìn Catirini mímọ ti o wà nì àwọn òkè Sinai, níbẹ, ni ilaji ọgọrùn ọdún kọkandinlogun ni Tiṣendọfu ti ri àkọsílẹ ti Bíbélì Giriki wa nínú rẹ̀.

Ni àfikún si awọn akọsilẹ kekeke Májẹ̀mú titun, bi ẹgbẹ̀rún mẹsan atunkọ atijọ láti inú èdè ojúlówó ni o wa. Pẹlu ọrọ bí ẹgbẹ̀rún mẹ́rindinlogoji lati ọdọ àwọn tí nwọn pé ara wọn ni baba ìjọ, èyí mú kí a fẹrẹ ṣe àtúnṣe gbogbo ọrọ ojúlówó nípa Ìṣẹ́ takuntakun.

Ko si iyemeji l'órí ọrọ kan nípa otítọ ẹkọ Ọlọrun ninu Májẹ̀mú titun.

**Didaju bí a ṣe fún wa ní ọrọ Bíbélì láti ìran diran jẹ ọna ara.**

# Inu ihò kumrani

Ni igba ti ojo ṣẹṣẹ tan ni ọdún 1947, ọmọdékùnrin kan lati ẹ̀yà Bẹdou tí ó nwa ewurẹ tí ó sá lọ, ri ẹnu ihò kan tí ó farasin ni ìhà òkè Kumrani ni ìwọ oòrùn òkun kiku.

O sọ òkúta sì ẹnu ihò náà. Sì ìyàlẹ́nu rẹ o gburo àmọ́ fifọ. O ya lẹnu ohun tí èyí lè jẹ.

Pẹlu ọfintoto ó ra pala wọ inú ihò àṣírí yi o sì rí ọpọlọpọ ife amọ ninu eyiti awọ tí a ka wa ninu wọn. Ìwọ̀nyí ni akọsilẹ àtijọ́ Bíbélì tí ó ṣe iyebíye, tí ó sì wá ní ipò didara lẹhin bí ẹgbẹ̀rún ọdún méjì dín ọgọrun.

Olùṣọ́ Àgùntàn yi mú awọ yi pẹlu rẹ, eyiti o jásí ìyàlẹ́nu bí àwọn onímọ̀ Ìjinlẹ ṣe ni ifẹ sí wiwa kiri, akọsilẹ pàtàkì yi tún lè keeka sii laarín àwọn onímọ̀ Ìjinlẹ àti ọmọwé oloju kokoro.

Iye owó lórí àwọn awọ akọsilẹ yi gòkè sì ẹgbẹgbẹ̀rún l'ọ́nà ẹgbẹ̀rún. Iru awárí nínú ihò Kumurani yi ti fa àwọn ọmọwé aiye sì ojú Ìṣẹ́.

Fún wa, awọ ìwé Aísáyà ni ó ṣe pàtàkì julọ nítorí pé ohun ni ìwé Bíbélì pipe tí ó pẹ ju.

Ko si iyemeji kan nípa ti jij'ojúlówó akọsilẹ eyiti a kọ ní saa kejì ṣaju Kristi. Nigbati a ba ṣe afiwe rẹ pẹ̀lú akọsilẹ Masorẹti (akọsilẹ Bíbélì Hébérù) ti iwe Aísáyà tí a kọ lẹhin ẹgbẹ̀rún ọdún. Àwọn ọmọwé wọnnì ri wipe kò sì ìyàtọ̀. Akọsilẹ wọnnì bá ara wọn dọ́gba.

Nitoripe akọsilẹ inú awọ ni ko ri ìdíwọ, gbogbo àwọn alátakò Bíbélì tí nwọn ti wipe ìwé Aísáyà tí jẹ kikojọpọ ni ọpọlọpọ ọdún sẹhin àti pé kò kúnjú òṣùwọ̀n ni òye otitọ ye.

L'ara àwọn àwárí inú ihò kumrani ní bí ojilenigba àti mẹwa akọsilẹ àwọn ọ̀rọ̀ májẹ̀mú laelae tí ó fi han wipe ẹ̀dà ìwé náà tí nwọn ni kun oju òṣùwọ̀n.

**Ọlọ́run ńṣọ Ọrọ Rẹ ki a le ni li ọwọ wa laisi àbùkù. Ọrọ Ọlọrun dabi apata: a kò lè ṣi ni 'po.**



**Ṣùgbọ́n Ọrọ Oluwa duro titi laelae.**

**Bíbélì – Pétérù kini 1 ẹsẹ 25**

## Ṣíṣe Bíbélì

### << Latíjọ àti Nisinyi >>



O ti ju ẹẹdẹgbẹ̀ta ọdún lọ tí Itẹsiwaju ìwé títẹ tí yipada ni aiye. Ṣáájú èyí, bí ẹnikẹ́ni bá nfẹ Bíbélì, ó ni lati ṣe adakọ rẹ pẹlu ọwọ ni, èyí sì ngba akoko àti ìnáwó.

Láti lè dabobo ọrọ ojúlówó rẹ, o ṣe pàtàkì láti mọ akọsilẹ tí ó pẹ ju, nítorí dídà kọ láti ibi kan sì èkejì ko le ṣai ni ewu aṣikọ.





Ṣíṣe àwárí ọrọ kíkọ jású iyanu. Akọsilẹ bíi ẹgbẹ̀rún mẹta ọrọ Bíbélì Hébérù ri bakanna pẹlu ara nwọn, ó sì ṣe ifidimulẹ àwọn ọrọ ti a mọ. Abala Bíbélì tí ó pẹ julọ, eyiti o w'aiye ni nkan bi ẹgbẹ̀rún ọdún mẹta àbọ̀ ni a ti mú wá sí akoko wa.



Bawo ni èyí ṣe ṣee ṣe? Ni fífi ọ̀wọ̀ fún ọ̀rọ̀ Mimọ Ọlọrun, àwọn Júù nkiyesi ọpọlọpọ ìlànà láti rí atunkọ tí ó kúnjú òṣùwọ̀n. Fún àpẹrẹ, ọrọ kan tabi ọ̀rọ̀ tí ó nfarahan léraléra ni nwọn nṣe àkíyèsí léraléra.

Loni, ọpọlọpọ ẹ̀dà Bíbélì ni ó ṣeé tẹ jáde ní àkókò kúkúrú lai na owo pupọ nipasẹ awọn ile itẹwe tí òde òní.

Bakannaa, ọpọlọpọ Bíbélì ni ó wa l'ori ẹ̀rọ ayélujára l'ọfẹ.



**Ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ Ọlọ́run gbilẹ, ó sì bí sii.**

Bíbélì – Ìṣe Aposteli 12 ẹsẹ 24

# Bíbélì àti imọ Ìjinlẹ

Bawo ni ìwé tí a ti kọ láti àkókò pipẹ bayi pẹlu awọn ọrọ rẹ l'ori ẹ̀dá ati ìtàn ṣe nkunju òṣùwọ̀n sibẹ? Kí ló dé tí imọ Ìjinlẹ ko lè kọlù Bíbélì?

Ọpọlọpọ àpèjúwe ni ó wà tí imọ Ìjinlẹ òde òní tí gbìyànjú l'ori ọ̀rọ̀ Bíbélì. Méjì nínú rẹ̀ nì yí:

## Njẹ aiye ha ri róbótó bí?



Ọlọ́run kò sọ pé aiye ri róbótó àti wipe oòrùn nyi aiye ka. Eyi ni ohun tí àwọn onímọ̀ Ìjinlẹ gbagbọ láti ọjọ pipẹ.

Bẹẹ kọ lo ri, Ọlọrun sọ nínú ọkàn nínú ìwé laelae Bíbélì. Jobu 26 ẹsẹ 7. **"O na ìhà àríwá s'ori ofurufu , O si fi aiye kọ s'ori òfo."**

## Ehoro ha njẹ àpọ̀jẹ?



Ni Léfítíkù 11 ẹsẹ 4 àti 6, O wipe: **"Nitorina ìwọ̀nyí ni ìwọ kì yio jẹ lára àwọn tí njẹ àpọ̀jẹ... Ehoro, nítorí tí o njẹ àpọ̀jẹ..."**

Ọrọ yi pé Ehoro njẹ àpọ̀jẹ ni nwọn ka si èké fún ọpọlọpọ ọdún.

Sibẹsibẹ, ní saa ọgọrun mọkandinlogun ọdún ni àwọn onímọ̀ Ìjinlẹ to mọ pe orísi igbọnsẹ méjì ni Ehoro ni. Ọkan ninu wọn ni ó njẹ padà kí ó le yọ èròjà iyebíye.



Bayi ni imọ Ìjinlẹ ṣe ni lati gba pẹlu Bíbélì lẹhin itọpinpin ọdún pupọ. Bakanna ni ọrọ Bíbélì kò lòdì sí ojúlówó imọ Ìjinlẹ ìsinsìnyí.





## Njẹ o ha le yatọ bi?

**Nje Ọlọ́run, tí O da agbaiye tí O sì fún wa ní ọrọ Rẹ (Bíbélì) lòdì sí ara Rẹ bí? Bẹẹ kọ, àti Ìfihàn Ọlọ́run yi, ÌṢẸ̀ DÁ àti ỌRỌ NA, ní nwọn fi idi ara nwọn múlẹ̀.**

# Ọrọ Inu Bíbélì

## > Ọlọrun Lo dá ọ

**Bẹẹ ni Ọlọrun dá enia ni aworan ara Rẹ; ni aworan Ọlọrun ni O daa, akọ ati abo ni O da nwọn.**
**Bíbélì – Gẹnẹsisi 1 ẹsẹ 27**

Ẹda Ọlọ́run ni ọ. Iru rẹ kan ṣoṣo ni ó wà laiye. Ni àfikún, agọ ara rẹ pẹlu gbogbo ojúṣe rẹ – ọpọlọ, ìṣesi, ẹya ara – ni Ọlọrun dá daradara. Ko si eyiti o dédé w'aiye lójijì nípa àkókò – bí àwọn ẹ̀kọ́ tí kò ní ifidimulẹ kan ṣe nsọ. Ọlọrun ti dá enia ni aworan ara Rẹ. Eyi ni ni lati jẹ aṣojú Rẹ nínú ẹ̀dá yi.

**Sibẹ sibẹ enia ṣubú sínú ẹṣẹ, O si yipada kúrò l'ọdọ Ọlọrun.**

## > Ọlọrun ka ọ kun "ẹlẹṣẹ̀", pẹlu

**Nítorí kò sí ìyàtọ̀; nítorí gbogbo enia ni ó ti ṣẹ, ti o sì kunna ogo Ọlọrun.** **Bíbélì – Romu 3 ẹsẹ 22 & 23**

Láti dẹ́ṣẹ̀ túmọ̀ sí ìṣe lai tẹríba fun Ọlọrun. Ko si iyatọ bóyá ẹṣẹ farahan bí ìṣe, tàbí tí a sọ sì gbangba, tàbí tí a ṣe nínú èrò. Jesu Oluwa sọ nígbà kan pé kíkorira enia burú bí ẹṣẹ ipaniyan ni!

## > Ọlọrun yio jẹ adajọ rẹ

**Niwọn bi a si ti fi lelẹ fun gbogbo enia lati kú lẹ̃ kanṣoṣo, ṣugbọn lẹhin eyi idajọ...**
**Bíbélì – Heberu 9 ẹsẹ 27**

Ọlọ́run jẹ mímọ àti olódodo. Eyi ni Ọ̀un yio ṣe ṣe idajọ ohun gbogbo tí kò wa ni ibamu pẹlu Ẹ̀dá Rẹ l'ọjọ kan. Bíbélì sọ gbangba pé ẹnikẹ́ni tí kò bá rí ìdáríjì ẹṣẹ rẹ gbà níláti máa retí iyapa kúrò l'ọdọ Ọlọrun titi lae. Yàtọ̀ sí Ọ̀run tí olúkúlùkù ẹniti o ni Idapọ pẹlu Jesu Oluwa yio wa. Ibòmíràn wa ti Bíbélì pé ni "ọrun apaadi" tàbí "inú iná". Ọlọrun kí yio si ni 'bẹ, bẹẹni ki yio si anfaani lati bàa sọ̀rọ̀.

**Sibẹ ireti wa !**

## > Ọlọrun ni ifẹ nla sì ọ

**Nipa eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmọ bíbi Rẹ̀ kanṣoṣo si aiye, ki awa ki o le yè nipasẹ Rẹ̀.** **Bíbélì – Jòhánù kini 4 ẹsẹ 9**

Wo orí agbelebu ni kalfari nibiti Jesu Kristi ti jiya láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ti O si jẹ irora ńlá. Ọlọrun kọ Ọ silẹ l'ori agbelebu nítorí O ru ẹṣẹ̀ wa. A kò lè ṣàkíyèsí ohun tí èyí túmọ̀ sí fún Jesu Oluwa, Ẹniti ko ni ẹṣẹ rárá.

**Ìwọ ha ri bi Ọlọrun ti fẹ́ràn rẹ to ?**

# Iranlọwọ Ọlọrun + Ọna ìgbàlà

A ya wa nipa kuro l'ọdọ Ọlọrun nipa ẹṣẹ. Ọlọrun ko le gba igbiyanju wa lati tún ara wa ṣe. Ọlọrun ninu iwa Mimọ Rẹ yio ṣe idajọ ibi. Ọna àbáyọ kan ṣoṣo ni ó wa: a ni lati gba ọ̀nà igbala ti o ti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run fúnra Rẹ wa.

**Nítorí Ọlọrun fẹ araiye to bẹẹ gẹ , Ti O fi Ọmọ bíbí Rẹ kan ṣoṣo fun ni, kí ẹnikẹ́ni tí ó bá gbaa gbọ má bàa ṣègbé ṣùgbọ́n kí ó le ni iye ainipẹ̀kun.** **Bíbélì – Jòhánù 3 ẹsẹ 16**

Láti lè fi Ọlọrun han, Ẹlẹda rẹ, Jesu Kristi di ènìyàn O sì tọ wa wa si aiye.

Jésù Kristi ti fi ifẹ Ọlọrun hàn wa. O Jẹwọ eyi nípa kiku fún ọ l'ori agbelebu ni kalfari. Gẹgẹbi aṣojú rẹ, O gba ijiya ẹṣẹ rẹ sì ori ara Rẹ- bí ìwọ bá gbaa gbọ.

**Bí ìwọ bá gba èyí gbọ ti o si Jẹwọ ẹṣẹ rẹ fún Ọlọ́run, Oun yio fún ọ ní idariji àti ìyè àìnípẹ̀kun.**

**Bi awa ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wa, olõtọ ati olododo li Oun lati dari ẹṣẹ wa jì wa, ati lati wẹ̀ wa nù kuro ninu aiṣododo gbogbo.**
**Bíbélì – Jòhánù kini 1 ẹsẹ 9**

Jésù Kristi wà láàyè! O jinde kuro ninu oku O sì padà sí ọrun.

Ihinrere ni a ti wàásù fún nkan bi ẹgbẹ̀rún ọdún méjì. Nipa bayi ni a fi Igbala lọ gbogbo ènìyàn. Ẹnikẹ́ni tí ó gba Jesu Kristi gbọ – Olugbala kan ṣoṣo – yio bọ lọwọ idajọ aiyeraiye Ọlọrun. Ẹnikẹ́ni tí ó gba Ìṣẹ́ irapada Jesu Kristi pẹ̀lú igbagbọ ni a ó sọ di olódodo níwájú Ọlọ́run.

**Awọn ẹniti a ndalare l'ọfẹ nipa ore-ọfẹ rẹ̀, nipa idande ti o wà ninu Kristi Jesu:**
**Bíbélì – Romu 3 ẹsẹ 24.**



# Àwọn ìlérí atọrunwa

Ni àkójọpọ, lẹta atọrunwa ni, Bíbélì wipe:

**1. Mimọ ni Ọlọrun.** > *O ni lati ṣe idajọ ki o si jẹ ẹṣẹ ní ìyà.*

**2. Ifẹ ni Ọlọrun.** > *O fẹ dárí gbogbo ẹṣẹ rẹ jì ọ.*

Ọlọ́run lè dárí ẹṣẹ rẹ jì ọ nítorí Ọmọ Rẹ, Jesu Kristi ti gba ẹ̀bi ẹṣẹ rẹ si ori ara Rẹ, ijiya fún ẹṣẹ, O si mu ohun gbogbo ṣẹ tí Ọlọ́run Mimọ fẹ.

Sibẹṣibẹ, láti rí ìdáríjì ẹṣẹ rẹ gbà, o ni lati wa si iwájú Ọlọ́run fún ìjẹwọ ẹṣẹ rẹ ni tòótọ́, kí ó sì gbagbọ pé Jesu Kristi kú l'ori agbelebu, àní fún ọ, gẹgẹbi Olugbala àti Olurapada.

**Nitorina Ọlọ́run ni jù ẹgbẹ̀rún kan àwọn akọsilẹ ọrọ Rẹ ti ko le yi pada fún ọ nínú Bíbélì.**

**Ìwọ yio ri diẹ ninu wọn nihin >>>**



**Ẹni ti o gba Ọmọ gbọ ni iye ainipẹ̀kun; ẹniti ko gba Ọmọ gbọ kí yio ri iye, ṣùgbọ́n ìbínú Ọlọrun nbẹ ni ori rẹ.**
**Bíbélì – Jòhánù 3 ẹsẹ 36**

**Ẹniti o ba gbọ ọrọ Mi ti o si gba Ẹniti O rán Mi ni iye ainipẹ̀kun, kí yio si wa si idajọ, ṣùgbọ́n ó ti re iku kọja sì iye.**
**Bíbélì – Jòhánù 5 ẹsẹ 24**

**Ṣùgbọ́n iye àwọn tí ó gbaa, àwọn ni O fi agbára fún lati di ọmọ Ọlọrun, àní àwọn tí ó gba orúkọ Rẹ gbọ.**
**Bíbélì – Jòhánù 1 ẹsẹ 12**

**Má bẹ̀rù, nítorí Mo ti rà ọ padà, Mo ti pé ọ ní orúkọ rẹ; tí Emi ni ìwọ.**
**Bíbélì – Aísáyà 43 ẹsẹ 1**

# Ọmọ oninakuna

## Ìtàn láti inú Bíbélì

Ọkùnrin kan ní ọmọkùnrin méjì. Èyí to kere ninu nwọn sọ fún bàbá rẹ̀, “Baba, fún mi ní ìpín mi ninu ohùn ìní rẹ.” O sì pin ohùn ìní rẹ fún nwọn. Lẹhin ọjọ diẹ, ẹyi àbúrò palẹ ẹru rẹ mọ, o si lọ sí ilu okere, nibẹ ni ó sì fi ìwà wọbia na ohun ini rẹ ni inakuna. Nigbati o sì ba gbogbo rẹ jẹ tan, ìyàn ńlá wa bẹ̀rẹ̀ si imú ni ilẹ̀ náà, ó sì bẹ̀rẹ̀ si ndi aláìní. O si lọ dá ara pọ mọ ọlọtọ kan ni ilu na, o sì rán lọ sí oko rẹ láti tọju ẹlẹ́dẹ̀. Ayọ ni ibà sì fi jẹ oúnjẹ ti àwọn ẹlẹ́dẹ̀ njẹ ni àjẹyó, ẹnikẹ́ni kò fi fun. Ṣùgbọ́n nigbati ojú rẹ wà lẹ, o ni, alagbaṣe Baba mi melomelo ni ó njẹ àjẹyó àti ajẹti, èmi sì nku fún ebi nihin! Èmi ó dìde emì ó sì tọ Baba mi lọ, èmi ó sì wí fún ń pe “Baba, èmi ti dẹ́ṣẹ̀ sì ọrun àti sí iwaju Rẹ, èmi kò sì yẹ ní ẹniti a bá maa pe ni ọmọ Rẹ mọ; fi mí ṣe ọkàn nínú àwọn alagbaṣe Rẹ.”
O sì dide, ó sì tọ Baba rẹ lọ. Ṣùgbọ́n nigbati o sì wa ni okere Baba rẹ ríi, aanu ṣe é, O si sure, O rọ mọ l’ọrun, O si fi ẹnu koo li ẹnu. Ọmọ na si wi fún n pe “Bàbá, èmi ti dẹ́ṣẹ̀ sì ọrun àti níwájú Rẹ, èmi kò yẹ li ẹniti a bá máa pe ni ọmọ Rẹ mọ.”
Ṣùgbọ́n Baba rẹ wí fún àwọn iranṣẹ rẹ pe, ẹ mú ààyò aṣọ wa ki ẹ si fi wọ ọ, kí ẹ sì fi òrùka sì ni ọwọ àti bàtà sì ẹsẹ rẹ. Ẹ sì mú ẹgbọrọ màlú abọpa wa kí ẹ sì paa; kí a máa jẹ, kí a sì maa ṣe àríyá; nítorí ọmọ mi yi ti ku, o si tún ye; o ti nu, a sì rí i. Nwọn si bẹ̀rẹ̀ si nṣe àríyá. Njẹ ọmọ rẹ̀ àgbà tí ó wà li oko; bí ó sì ti mbọ, tí ó sunmọ etile gbọ orin àti ijo. O sì pe ọkan ninu awọn ọmọ ọ̀dọ̀ wọn, ó béèrè, kini a mọ nkan wonyi sì?
O si sọ fún pé, “aburo rẹ dé; nítorí o ríi padà ní alafia àti ìlera, baba rẹ sì pa ẹgbọrọ màlúù àbọ̀pa.” Ṣùgbọ́n ó binu, ó sì kọ láti wọlé; baba rẹ sì jáde, ó sì wá Iṣipẹ fún u. O sì dáhùn ó wí fún bàbá rẹ̀ pé, “woo láti ọdún melo nwọnyi ni èmi ti nsin ọ, èmi ko sì ru òfin rẹ ri: ìwọ kò sì ti fi ọmọ ewurẹ kan fun mi láti fi bá àwọn ọrẹ mi ṣe àríyá. Ṣùgbọ́n nigbati ọmọ rẹ yi de, ẹniti o fi panṣágà run ọrọ̀ rẹ, Ìwọ sì ti pa ẹgbọrọ màlúù àbọpa fún u.” O sì wí fún pé, “Ọmọ, nigba gbogbo ní ìwọ nbẹ lọdọ mi, ohun gbogbo tí mo sì ní, tìrẹ ni. O yẹ ki a ṣe àríyá kí a sì yọ; nítorí àbúrò rẹ yi ti ku, o si tún ye, ó ti sọ nu, a sì rí i.“

Bíbélì – Luku 15 ẹsẹ 11-32




# Ẹsin Pupọ – Gbogbo rẹ ha jẹ Ọlọrun kan bi?

O jẹ ohun tí ó wọ́pọ̀ ni sísọ pé àwọn ẹsin dárí sì ọ̀dọ̀ Ọlọrun kanna, àwọn ọna nwọn lo yàtọ̀.

Eyi ṣe l'òdì sí koko ọrọ Inu Bíbélì láti ẹnu Jesu Kristi. "Emi ni ọna, otitọ ati iye. Ko si ẹnikẹ́nití ó lè wá s'ọ̀dọ̀ Baba, bikoṣe nipasẹ mi." (Jòhánù 14 ẹsẹ 6). A ti sẹ Otitọ yi lapapọ l'aiye òde òní.

Fún àpẹrẹ, afiwe korani àti Bíbélì fi hàn gbangba pé "Alla tí Imale" kò lè jẹ Ọlọrun ti Bíbélì:

**KORANI** …nitorina gba Alla ati awọn iranṣẹ rẹ gbọ, kí ó má sì ṣe wipe "Mẹta"... Ọlọrun kan ni Alla A gbee ga ju kí O ni ọmọ.
Kurani – Láti inu sura kẹrin.

**BÍBÉLÌ** **Nítorí Ọlọrun fẹ araiye to bẹẹ gẹ, ti o fi Ọmọ bíbí rẹ̀ kan ṣoṣo fun ni, kí ẹnikẹ́ni tí ó bá gbaa gbọ má bá ṣègbé, ṣùgbọ́n kí ó le ni iye ainipẹ̀kun.** Bíbélì – John 3:16



**KORANI** Àti fún ọrọ wọn, "Nitootọ, a ti pa Mèsáyà,Jesu, ọmọ Maria,iranṣẹ Alla." Nwọn ko sí paa,bẹni nwọn ko kan mógi, ṣùgbọ́n ẹlòmíràn ni a mu ki ó jọọ l'ójú wọn.
Kurani – Láti inú sura kẹrin.

**BÍBÉLÌ** **Nítorí pé wèrè ni ọ̀rọ̀ agbelebu sì àwọn tí ó nṣegbé; Ṣùgbọ́n si àwa ti a ngbala, agbára Ọlọ́run ni...Ṣùgbọ́n a nwasu Kristi ti a kan mọ agbelebu, ikọsẹ fún àwọn Júù, àti wèrè fún àwọn Heleni.**
Bíbélì – Kọ́ríńtì kini 1 ẹsẹ 18 àti 23

Korani sẹ jalẹ pé "Alla" ni ọmọ, Mẹta-lọkàn àti otitọ pé Jesu Kristi kú l'ori agbelebu! Ṣùgbọ́n Ọlọ́run Bíbélì jẹ Ọlọrun alààyè. Ninu ifẹ sì iwọ àti èmi, O fi Ọmọ Rẹ ṣe ètùtù fún ẹṣẹ- wipe Jesu jiya idajọ Ọlọrun ti O lọ si ikú. Nípa báyìí "Alla" kò lè jẹ Ọlọrun ti Bíbélì, tí O jẹ Baba Jesu Kristi Olúwa.

## Àkíyèsí: Igbagbọ tí Bíbélì kí nṣe ẹsin!

**Ni oniruru ẹsin aiye yí, ènìyàn ngbiyanju láti wá ọna sì ọ̀dọ̀ Ọlọ́run nípa ara rẹ.**

**Ṣùgbọ́n Bíbélì fi Ọlọrun mimọ tí O sọkalẹ ninu Ọmọ Rẹ Jesu Kristi hàn wa, kí gbogbo ẹni tí ó bá gbaa gbọ ti o si Jẹwọ ẹṣẹ rẹ fún lè ní igbala.**

**Ṣùgbọ́n fún ẹniti ko ṣíṣẹ tí ó si gba ẹniti nda alaiwabi Ọlọrun lare, a ka igbagbọ rẹ si òdodo.**
Bíbélì – Romu 4 ẹsẹ 5

# Wo ojo iwaju



Bíbélì fún wa ní ọrọ to daju nípa ọjọ iwájú.

Laala àti ibanujẹ yi wa ka kiri ní àkókò yi: ikú, ìwà àìmọ , ìwà ipá, ìyàn, ogun, ìjàmbá, idamu ọrọ aje, Idamu, ipanle...!

Sibẹ, Jesu Kristi yio padà wa l'aipẹ! Ọlọ́run sọ fún wa dájú nínú Bíbélì pé ṣáájú kí Jesu kí ó tó padà wá, àwọn nkan wọnnì yio ṣẹlẹ̀. Oluka Bíbélì pẹlu mọ bí nkan yio se tẹ síwájú:

Ọlọ́run yio ṣe idajọ aiye, tí ó ti yipada kúrò ní ọ̀dọ̀ Rẹ ti o si nri sínú ẹṣẹ. Sibẹ Ọlọ́run **"pàṣẹ nisisiyi fún gbogbo enia níbi gbogbo láti ronupiwada, nítorí O ti yàn ọjọ kan nínú eyiti yio ṣe idajọ aiye..."**
(Ìṣe Aposteli 17 ẹsẹ 30 àti 31).

Eyi yio ṣẹlẹ̀ nipasẹ Ọmọ Rẹ Jesu Kristi, Ẹniti yio padà wa l'aipẹ láti ọrun fún idajọ. Òun, tí a kẹ́gàn tí a sì kan mọ́'gi, yio padà wa bí àṣẹgun ati àṣẹ onidajọ tí ó ga ju: Òun ni ẹni na **"tí a ti ọwọ Ọlọrun yàn ṣe onidajọ ààyè àti oku"** (ìṣe Aposteli 10 ẹsẹ 42).

**Idajọ daju- ṣugbọn ìrètí mbẹ fun ọ!**



Bíbélì sọ tẹ́lẹ̀ lẹkun rẹrẹ ni tí bibi Jesu Kristi ati iku ati ajinde Rẹ láti ọpọlọpọ ọdún sẹhin. Bí Jesu Kristi ṣe fi ẹ̀mí Rẹ lè lẹ fún ọ. Ọlọrun fi ore-ọfẹ àti ìdáríjì fún ọ l'oni.

**Wa loni, ní Ọlọrun wí- ọla lè pẹ ju:**

**Kiyesii, nisisiyi ni akoko ìtẹ́wọ́gbà; kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ ìgbàlà.** Kọ́ríńtì kejì 6 ẹsẹ 2

Gba ẹbùn Ọlọ́run, ìwọ yio si ni igbala aiyeraiye kúrò nínú idajọ Ọlọrun. Láti ṣe èyí, ó ni lati tọ Ọ wa pẹlu ìjẹwọ ẹṣẹ rẹ.

Ọlọ́run Olódùmarè sọ tẹ́lẹ̀ nitootọ. Ko si ẹniti o lè ṣe é. Ọgọrọrun àsọtẹ́lẹ̀ bibeli ni ó ti ṣẹ pẹlu ìdánilójú. Bibeli sọ tẹlẹ nipa: àwọn ìjọba ni Ọgọrọrun ọdún ṣáájú; bíbí Jesu Kristi; bibajẹ Jerúsálẹ́mù jẹ ní àádọ́rin ọdún lẹhin ikú Jésù; fifọnka kiri àwọn Júù sì gbogbo aiye. àti bẹẹ bẹ lọ.

**Gbogbo èyí fi hàn li ọna àrà pé Bíbélì jẹ ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.**

Bíbélì fún àpẹrẹ, sọ nípa àwọn juu (àwọn ènìyàn Ísírẹ́lì) ni Diutarónómì 28 ẹsẹ 64 àti 65: **"Oluwa yio si tú ọ ká sínú enia gbogbo, láti opin ilẹ̀ kan de òmíràn... Àti laarin awọn orílẹ̀ èdè wọ̀nyí ni ìwọ kì yio ri irọrun bẹẹni atẹlẹsẹ rẹ kì yio ri ibi ìsinmi."**

**>> Gbe yẹwo fúnra rẹ boya àwọn nkan wonyi ko tii ṣẹ!**

# Kúkúrú ni Àkókò

## Yio si kọja lọ bí aworan

**Loni** ó ni lati múra silẹ láti pàdé Ọlọrun.
Ṣé ìwọ ha fẹ máa gbé ọrọ yiyipada sì Ọlọrun ti ni?
Yio pẹ ju fun ọ ní ọjọ́ kan!

























**Nitorinaa:**

**Ba Ọlọrun la ja.**

Bíbélì – Kọ́ríńtì kejì 5 ẹsẹ 20

# Koko Àkíyèsí nípa Bíbélì







"Mo kọ Bíbélì Mimọ lẹkun rẹrẹ fún ogóji ọdún. Igbagbọ mi l'agbara sí loni ju ogóji ọdún sẹhin. Otitọ ni gbogbo ìlérí rẹ."

Hudson Taylor (1832-1905), iranṣẹ sì china

"Mo ti ka Bíbélì Mimọ daradara, mo si ro wipe Ìwé atijọ yi...ni ọla ati ẹwà ede ju àwọn iwe miran, bi o ti wu ki o pẹ to tabi ede ti a fi kọ wọ́n."

Sir William Jones (1746-1794), ọkan lára ẹni nla ti o ni ẹ̀bùn ede (mejidinlọgbọn) ọjọgbọn ìlà oòrùn .

"Wo bí ọrọ àwọn onímọ̀ Ìjinlẹ wa ṣe kunna to pẹlu gbogbo aidọgba rẹ ni afiwe Bíbélì. Njẹ ó ṣèèṣe kí ìwé, tí ó rọrùn tí o sì pe bayi, kun fun ọrọ enia nikan?"

Jean Jacques Rouseau (1712-1778), onímọ̀ Ìjinlẹ



"Bíbélì jẹ ìwé ìtàn araọtọ àti ojúlówó ìwé orísun itan. O ti sọ ẹgbẹgbẹ̀rún ohun iṣẹmbaiye di rírí, ó sì ti ṣe ọpọlọpọ ìwé kika lórí àṣà àtijọ́. Bíbélì má nfihan pé otitọ ni, ni ibikíbi tí ayẹwo bá ti ṣèèṣe, Ni ṣíṣe àpèjúwe ohun kékeré àti ohun ńlá."

Dave Balsinger àti Charles E. Seller, Onímọ̀ Ìjinlẹ Amẹrika

"Ninu Bíbélì ò lè rí otitọ ńlá tí ó kọjá imọ ọkan enia, ó sì fi hàn bí ìrònú wa ṣe kéré mọ.
Sibẹṣibẹ, nínú pataki ọrọ rẹ, Bíbélì ko nira láti mọ."

Charles H Spurgeon (1834-1892), Oníwàásù ìsọji

"Bíbélì nikan ni ọrọ ti o ti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run wa ti o wa ni títẹ sínú iwe ti o si wa ni èdè enia. Ìdí nì yí ti Bíbélì fi jẹ araọtọ tí ó sì ṣe gbẹkẹlé nínú àkójọ pọ ọrọ rẹ. Kí nṣe imọ aiye, Ìjinlẹ tàbí ero to ngbiyanju àti ṣàtúnṣe Bíbélì. Ni idakeji, Bíbélì ni ó nṣe afọmọ ero wa."

Prof . Dr. Werner Gitt. - Olori tẹlẹ ni abala ilé-iṣẹ́ tí imọ ẹrọ ibanisọrọ ni PTB Braunschweig.

**O rọrun láti pé Bíbélì ni ìjà pé kò kun ojú òṣùwọ̀n, ṣùgbọ́n ohun miran ni lati fi idi rẹ múlẹ̀.**

# Atunkọ láti inú Ojúlówó èdè

Ìṣẹ́ tí ó nira ni lati túmọ̀ Bíbélì.

Èdè Hébérù tí Májẹ̀mú laelae ati Griki tí Májẹ̀mú titun ni àkójọ pọ ọrọ ti o tobi nikan láìní àmì idanuduro. Ìdí ni yi ti o fi nira fún àwọn akẹkọ èdè lati mọ ibi tí ẹsẹ ọrọ ti bẹ̀rẹ̀.

Ni àfikún, èdè Hébérù kò ní àwọn ọrọ bíi a,ẹ,i,o,u. Ṣugbọn àwọn ọrọ konsonati nikan bíi b,k,t àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ

O ni lati ṣe afikun ọrọ wọnnì fúnra rè. Gẹnẹsisi 1 ẹsẹ 1 fun wa yio ri bayi nigbana:

LTTKỌṢỌLỌRNDỌRNNY

Njẹ ìwọ ha le mọ: "Li atetekọṣe Ọlọ́run da ọrùn on aiye" ninu ọrọ wọ̀nyí ? Àwa ní láti dupẹ fun àwọn ọmọ́wé tí nwọn ṣe àwárí àwọn iwe atijọ wọ̀nyí tí nwọn si túmọ̀ wọn.



Ni èdè oyinbo, ọpọlọpọ Bíbélì ni ó wa. Nwọn yàtọ̀ ni tí bí nwọn ṣe túmọ̀ ojúlówó èdè rẹ. Pupọ àwọn Bíbélì ìgbàlódé ni nwọn yàgò pupọ kúrò ní ojúlówó èdè tó bẹẹ gẹ tí ọrọ miran sọ agbára rẹ nu, fún àpẹrẹ tí a bá túmọ̀ "ẹṣẹ" sì "àṣìṣe".

Tí ó bá fẹ́ mọ daju pe o nka ọrọ Ọlọrun ti a kọ sínú Bíbélì, a gba ọ ní iyanju kí ó wà Bíbélì tí ìtumọ̀ rẹ sunmọ èdè ojúlówó.

Loni, Bíbélì tàbí apakan nínú rẹ̀ wa ni nkan bíi ẹgbẹ̀rún mẹta èdè. Bíi ipa mẹtadinlọgọrun nínú ọgọrun àwọn tí ó wà laiye ni ó ṣeé ṣe fún lati ka ọrọ Ọlọrun.

Sibẹ àwọn olutumọ tí ó fi ara nwọn silẹ láti túmọ̀ Bíbélì sí àwọn èdè pupọ ni ìgbèríko aiye. Eleyi lè pupọ, níwọ̀n bí nwọn yio ṣe kọ̀kọ̀ dá èdè kíkọ silẹ.

**Bíbélì tí di ìwé tí a mọ ju àti ìwé tí o gbajumọ julọ ni aiye. Iye àwọn èdè tí a ti túmọ̀ rẹ sì láti bí igba ọdun sẹhin tí goke pupọ sìi.**

Ni ọdún 1800, a ti túmọ̀ rẹ sì èdè marun dín lọgọrin.
Ni ọdun 1900, a rí ojidinlẹgbẹta ó dín mẹta itumọ.
Ni ọdun 1953, a rí ẹgbẹ́fà dín mẹtalelọgbọn.
Ni ọdún 1978, iye rẹ tí di ẹgbẹ̀rún kan àti ẹgbẹ̀ta.
Ni ọdún 2017, a ti túmọ̀ Bíbélì sí bíi ẹgbẹ̀rúnmẹta èdè.!

# Ìwé fún Gbogbo Eniyan

>ogójì ènìyàn ló kọọ
>ọgọrọrun lo túmọ̀ rẹ,
>ẹgbẹgbẹ̀rún lo tẹ ẹ,
>ẹgbẹlẹgbẹ  lo nkaa.

Ko si ìwé miran ti o gbilẹ sì èdè àti àṣà bí ti Bíbélì. Ohun ni ìwé tí a nka julọ l’aiye.

Ni awọn ojú ewe mẹta yi, ẹsẹ Bíbélì láti Jòhánù 3 ẹsẹ 16 ni a lè ka ni èdè pupọ.

**Nítorí Ọlọrun fẹ araiye to bẹẹ gẹ tí ó fi ọmọ bíbí Rẹ kan ṣoṣo fun ni, kí ẹnikẹ́ni tí ó bá gbaa gbọ má bàa ṣègbé ṣùgbọ́n kí ó le ni iye ainipẹ̀kun.**

Ẹsẹ yi, tí a tún pe ni “ọkàn Bíbél“ ni ó ṣe àkójọ pọ ìhìn rere Ọlọ́run sì ẹda eniyan.

> **Ọlọrun féràn rẹ to bẹẹ tí O fi Ọmọ Rẹ fún ọ.**

> **Nípa igbagbọ nínú Rẹ, a ó gbà ọ la.**



## Èdè Oyinbo — Ilẹ Gẹẹsi

*For God so loved the world, that He gave His only begotten Son, that whoever believes in Him should not perish but have everlasting life.*

## Heberu — Isirẹli

כִּי כֹּה אָהַב אֱלֹהִים אֶת הָעוֹלָם עַד כִּי נָתַן אֶת בְּנוֹ יְחִידוֹ
לְמַעַן לֹא יֹאבַד כָּל הַמַּאֲמִין בּוֹ, אֶלָּא יִנְחַל חַיֵּי עוֹלָם.

## Èdè Tọki — Tọki

**Çünkü Tanrı dünyayı o kadar çok sevdi ki, biricik Oğlu‘nu verdi. Öyle ki, O‘na iman edenlerin hiçbiri mahvolmasın, hepsi sonsuz yaşama kavuşsun.**

## Bẹngali — India

কারন ঈশ্বর এই জগতকে এতোই ভালবাসেন, যে, তিনি তার একমাত্র জন্মগ্রহণ পুত্রকে দিলেন যেন যে কেউ সেই পুত্রের উপর বিশ্বাস করে সে বিনষ্ট হয় না  বরং অনন্ত জীবন লাভ করে

## Èdè Họngiri — Họngiri

*Úgy szerette Isten a világot, hogy egyszülött Fiát adta, hogy aki hisz őbenne, el ne vesszen, hanem örök élete legyen.*

## Bọ́mese — Mianma

ဘုရားသခင်၏သားတော်ကိုယုံကြည်သောသူအပေါင်းတို့သည်ပျက်စီးခြင်းသို့မရောက်ထာဝရအသက်ကို ရစေခြင်းငှါဘုရားသခင်သည်မိမိ၌တပါးတည်းသောသားတော်ကိုစွန့်တော်မူသည်တိုင်အောင် လောကီသားတို့ကိုချစ်တော်မူ၏။

## Ṣainisi — Ṣaina

神爱世人，甚至将祂的独生子赐给他们，
叫一切信祂的，不至灭亡，反得永生。

## Amuhariku — Ẹtiopia

**በእርሱ የሚያምን ሁሉ የዘላለም ሕይወት እንዲኖረው እንጂ እንዳይጠፋ እግዚአብሔር አንድያ ልጁን እስኪሰጥ ድረስ ዓለሙን እንዲሁ ወዶአልና።**

## Giriki — Girisi

**Επειδή, με τέτοιον τρόπο αγάπησε ο Θεός τον κόσμο, ώστε έδωσε τον Υιό του τον μονογενή, για να μη χαθεί κανένας ο οποίος πιστεύει σ' αυτόν, αλλά να έχει αιώνια ζωή.**

## Larubawa — Íjíbítì ati ilẹ Araabu

لأنَّهُ هكذا أحَبَّ اللهُ العالَمَ حتَّى بَذَلَ
ابنَهُ الوَحيدَ، لكَيْ لا يَهلِكَ كُلُّ مَنْ يؤمِنُ بهِ،
بل تكونُ لهُ الحياةُ الأبديَّةُ.

## Èdè Rọṣia — Rọṣia

**Ибо так возлюбил Бог мир, что отдал Сына Своего единородного, дабы всякий, верующий в Него, не погиб, но имел жизнь вечную.**



## Pọtugi — Pọtuga

*Porque Deus amou o mundo de tal maneira que deu o seu Filho unigênito, para que todo aquele que nele crê não pereça, mas tenha a vida eterna.*

## Japanisi — Japani

神は、実に、そのひとり子をお与えになったほどに、世を愛された。それは御子を信じる者が、ひとりとして滅びることなく、永遠のいのちを持つためである。

## Tẹlugu — India

దేవుడు లోకమును ఎంతో ప్రేమించెను. కాగా ఆయన తన అద్వితీయ కుమారునిగా పుట్టిన వానియందు విశ్వాసముంచు ప్రతివాడును నశింపక నిత్య జీవము పొందునట్లు ఆయనను అనుగ్రహించెను.

## Pọliṣi — Polandi

Albowiem tak Bóg umiłował świat, że Syna swego Jednorodzonego dał, aby każdy, kto weń wierzy, nie zginął, ale miał żywot wieczny.

## Jamani — Jamini

**Denn so hat Gott die Welt geliebt, dass er seinen eingeborenen Sohn gab, damit jeder, der an ihn glaubt, nicht verloren gehe, sondern ewiges Leben habe.**

# O le Ka Bibeli ni Awọn ọna orişirişi:

O le kaa
bi **nkan akọsilẹ atijọ** lati ni itẹlọrun iwadi rẹ.

O le kaa
bi **iwe itan** lati gba alaye nipa awọn akoko ti o ti kọja.

O le kaa
Kiki fún **ọgbọn** lati ṣe itupalẹ ati ṣe idajọ awọn alaye rẹ.

Sibẹṣibẹ, o tun le ka Bibeli
**Pẹlu igbagbọ,** gẹgẹ bi ifiranṣẹ Ọlọrun taara si ọ loni.

Ti o ba ka Bibeli bi ifiranṣẹ lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ifẹ Ọlọrun, eyiti o le ri ninu Jesu Kristi, le sọ si ọkan rẹ. Nígbà náà, ẹ̀rí ọkan rẹ náà yiò ní ìmọ́lẹ̀ l'ọ́dọ̀ Ọlọ́run gẹ́gẹ́ bí Jésù ṣe tan ìmọ́lẹ̀ nípa iṣe àti ọ̀rọ̀ Rẹ̀.





Ohun idunnu

## Bibeli titẹ ti o kere julọ

**> Bibeli pipe**

Bíbélì títẹ̀ tí ó kéré jù lọ tí a mọ̀ jẹ́ pé ó tóbi díẹ̀ ju pọ́un méjì ẹyọ kan lọ. Bíbélì yi gùn ní sẹ̀ǹtímítà 2.8, fífẹ̀ sẹ̀ǹtímítà 3.4, ó sì nípọn sẹ̀ǹtímítà kan, ó sì ní àwọn ojú ìwé bi ẹgbẹrun kan àbọ̀ o le mẹrinla. O le ka ohun gbogbo daradara pẹlu dingi ìkàwé.



## Majẹmu Lailai ti o kere julọ l'aiye

**> lori ẹrọ ìgbàlódé**

Ni ọdun 2008, awọn onimọ ijinlẹ sayẹnsi Israẹli lati ile ẹkọ imọ ẹrọ ni Haifa gbiyanju lati kọ Majẹmu Lailai lori idaji milimita onigun mẹrin kan. ọrọ ti o ju ẹgbẹrun l'ọna ō dunrun lọ ti Majẹmu Lailai ni ede Heberu ni a fi pamọ sori ẹrọ ti iwọn rẹ kò ju horo ṣuga. Pẹlu iranlọwọ ti imọ-ẹrọ nikan ni a le ṣe iru horo kekere bẹ. Lati ka ọrọ naa, ẹrọ naa iba ti ni lati yipada ki o sí gbooro ni ọna ẹgbẹrun mẹwa.

## Ṣe o tun le kere si?

**> DNA- ọna ipamọ alabọde ti ọjọ iwaju**

Ọlọrun, Ẹlẹdà, ti gbin ibi ifipamọ ti o wuyi sinu agọ ara wa kọọkan. Agbara ipamọ rẹ kọja gbogbo ibiti oye eniyan mọ l'oni: o jẹ okun DNA ti o ni iwọn ila opin ti milimita meji milionu. Inu rẹ ni ọpọlọpọ ainiye ohun elo dídá gbogbo eniyan mọ wa.

Bí a bá ní ohun èlò DNA tí a ti múra sílẹ̀ tó ìwọ̀n hóró ṣúgà kan tí ó ní ìbámu pẹ̀lú kíkọ̀wé àti ìmọ̀ kíkà rẹ̀, a lè "fipamọ́" ó fẹ́rẹ̀ẹ́ tó bílíọ̀nù kan àwọn Bibeli tí ó pé pérépéré lórí rẹ̀. Awọn onimọ ijinlẹ sayẹnsi gbagbọ pe awọn ibi ifipamọ DNA nla yio wa ni ọdun diẹ si.

# Jesu – Ọrẹ Wa Ti o Dára Julọ



Awọn ọmọde ni ifẹ Rẹ. O fi inu didun gbe awọn ọmọ kekere ni apa Rẹ.

O jẹ alagbara! Iji ru igbi s'oke, ọkọ oju-omi ti O joko ninu rẹ sí wa ninu ewu nla. O ba afẹfẹ wi, okun si dakẹ.

Ó mu àwọn aláìsàn lára dá, ó sì ṣàánú gbogbo eniyan – àwọn tálákà àti ọlọ́rọ̀ bakanna.

Ó rí ẹ̀ṣẹ̀ l'ọ́kàn wọn, ti nṣe orísun idamu gbogbo. Sibẹṣibẹ obinrin kan ti o ni orukọ buburu ko bẹru Rẹ. Ó ńsọkún nítorí ìwà búburú rẹ̀, ó tọ̀ọ́ wá, Ó sì dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ jì í.

Ni ọjọ kan nwọn muu ni igbekun! Nwọ́n pinnu pé ó ní láti lọ. O si jẹ ẹnití O dara ti O sì mọ-ati bayi ko baramu pẹlu ipo ẹṣẹ wọn. Nítorí náà, nwọ́n pinnu pé ó sàn kí nwọ́n kuku mu kuro.

**Nwọn kàn án mọ́ àgbélèbú láti kú.**

Ṣugbọn nwọn ko ni òye pe O mọ gbogbo rẹ tẹlẹ! Òun, Ọmọ Ọlọ́run, ti ọ̀run wá láti kú. Ó fẹ́ gba gbogbo wa là lọ́wọ́ ikú, ikú aiyéraiyé.

**Ṣugbọn kini ayọ!** Jesu Oluwa ko duro ninu iku. O dide lati ibojì. O wa láàyè o si wa ni ọrun bayi. Ó rí wa ó sì ṣàánú wa. Ó mọ̀ ọ́, O sì fẹ́ dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì ọ́ tí o bá kabamọ̀ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ tí o sì jẹ́wọ́ wọn fún Un, gẹ́gẹ́ bí obìnrin ti a sọ nipa rẹ̀ ní iṣàájú.

"Bẹẹni", ni ohun ti Oun yio sọ nigbana, "Mo le dari ẹṣẹ nyin jì nyin nisisiyi nitori mo ti ru ijiya fun wọn l'ori agbelebu

**Ati lẹhinna itan tuntun yio bẹrẹ:** Itan ti igbesi aiye tuntun rẹ, ti o yipada, nitori yio yatọ patapata si ohun ti o wa titi di isisiyi. Oun yio di ọrẹ to dara julọ. Iwọ yio ni anfani lati jiroro lori ohun gbogbo pẹlu Rẹ (eyi ni a npe ni "gbigbadura"). Lẹhinna iwọ yio fẹ lati ka Bibeli funrararẹ lati le mọ Ọ daadaa si.

Bibeli yio di iwe iyanilẹnu fun ọ. Dajudaju iwọ yio fẹ lati ka nkan nipa Jesu Oluwa lojoojumọ.

O kan fẹ lati jẹ ọrẹ rẹ to dara julọ!





# Ipalẹ̀mọ Nla

Ẹ wo bí ògiri yàrá ọ̀dọ́mọkùnrin náà ti burú tó! O ti boo pẹlu awọn fọto idọti ati awọn posita. Ni ọjọ kan aburo baba rẹ, olorin kan, wa fun abẹwo. O ni ibanujẹ nipa ohun ti o fi oju ri ṣugbọn ko sọ ohunkohun.

Ní ọjọ́ díẹ̀ lẹ́hìn náà, ọmọ ẹ̀gbọ́n náà gba àwòrán kan tó fani mọ́ra tó sì ṣe iyebíye látI ọ̀dọ̀ ẹ̀gbọ́n rẹ̀. Iṣe ọnà yi gba aye ọlá lara ogiri yara, ati pe a yọ awọn fọto miran  kúrò lati wa aye fun un.

Lati akoko yẹn, o dabi ẹnipe ifarahan ti o yatọ, ti o sí mọ ju ti tẹlẹ ti jọba ninu yara yi ati pe iwe àlẹ̀mọ́ ogiri kan lẹhin ekeji ni o nkuro. Nwọn ko ba yara na mu mọ.

Bi o bá bẹ̀rẹ̀ sí nka Bíbélì, ó ṣeé ṣe kó jẹ́ pé èyí àti ìyẹn yio pòórá lára ògiri rẹ, patako ìwé tàbí orin rẹ. Boya diẹ ninu awọn ila ere tabi awọn ọna miran lori ẹrọ kọmputa rẹ tabi foonu rẹ yio paarẹ. Tani o mọ - boya nkankan lati awọn kọ̀rọ̀ ọkan rẹ yio parẹ pẹlu.

**Nítorínà, bí ẹnikẹ́ni bá wà nínú Kristi, ó di ẹ̀dá titun; ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, ohun gbogbo ti di titun. Ati idapọ  kini imọlẹ ni pẹlu òkunkun?** Bíbélì – Kọ́ríńtì keji 5 ẹsẹ 17, 6 ẹsẹ 14

# Iwe itan ti o l'adun julọ ni agbaiye

"Mama, ma duro, tẹsiwaju ni kika! Itan naa ni adun, jọwọ kaa de opin!" Nitootọ, itan naa dun lọpọlọpọ:



**Jósẹ́fù, tí àwọn arákùnrin rẹ̀ kóríìra ni nwọn ju, sínú kòtò omi kan, nwọ́n fà á jáde lẹ́hìn náà, wọ́n sì tà á gẹ́gẹ́ bí ẹrú sí Íjíbítì, níbi tí nwọ́n ti jù ú sẹ́wọ̀n bi o tilẹ̀ jẹ́ pé kò ní ẹ̀ṣẹ̀. Síbẹ̀ ó di olórí ìjọba Íjíbítì, ẹni tí ó gba ìdílé rẹ̀ àti gbogbo orílẹ̀-èdè náà là nígbà ìyàn.**

Bíbélì – Genesisi 37 - 50

Bíbélì kún fún àwọn ìtàn gidi ti o wúni l'órí bí èyí tí nwọ́n ńmú ni ronú jinlẹ̀, síbẹ̀ ti o dára fún ọkàn.

Bíbélì – Dáníẹ́lì 3

**Ronú nípa àwọn ọ̀rẹ́ Dáníẹ́lì mẹ́ta, tí nwọn kò fẹ́ tẹrí ba níwájú òrìṣà ọba tí nwọ́n sì jù wọ́n sínú iná ìléru nítorí èyí; sibẹsibẹ, nwọn jade kuro laini ipalara.**



**Bíbélì jẹ́ ìwé amóríyá, àní fún àwọn ọ̀dọ́ pàápàá!**

# Nje o ti jẹ Bẹladona ri ?

(Atiropa bẹladona)



Majele ọgbin bẹladónà jẹ ewu fún ẹmi eniyan. "Ṣugbọn mo fẹ lati gbiyanju nitori pe mo ni idaniloju pe ki yio ṣe ipalara fun mi bi ti awọn ẹlomiran."

Ti ẹnikẹni ba sọrọ bẹẹ, yio dara lati ṣiyemeji ilera wọn. Bí ó ti wù kí ó rí, ǹjẹ́ a kì í ṣe bẹ́ẹ̀ nígbà mìíràn bí? A ti jinlẹ púpọ̀ si aiye awọn oniroyin, nibiti nwọn ti yi ilana Ọlọrun nipa igbeyawo ati idile pada. A ka awọn iwe atẹjade ninu eyiti a ṣe apejuwe awọn iṣe iṣẹ okunkun, nibiti irọ ati ayinike wa lori ẹrọ. A fẹ lati "gbiyanju" awọn nkan wọnyi lati gbiyanju fi ara wa han pe a ti kọja ati ni ipalara nipasẹ wọn.

Bíbélì sọ pé ki "a di" etí wa, ki á sì "di ojú wa" kí a má bàa gbọ́ tàbí rí ibi (Aísáyà 33:15). Nitorina, imọran ti o dara ni pe:

**>>> Maṣe jẹ eyikeyi eweko Bẹladona !**

Bẹ̄ni ki o ma fi eyikeyi sinu ile rẹ! Yago fun ohun gbogbo ti ko ni ibamu pẹlu awọn ero Ọlọrun. Ọlọ́run fẹ́ dáàbò bò wá lọ́wọ́ àwọn ipa ẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ọ̀nà ibi, Yi O sì ṣe bẹ́ẹ̀ bí a bá ka Bíbélì. Ọrọ Ọlọrun jẹ mimọ ati otitọ, o wa laaye láéláé. Ó fi ọ̀nà àbáyọ sí ojúlówó ayọ̀ àti alafia tòótọ́ hàn ọ́.

**Ọ̀rọ̀ rẹ ni fìtílà fún ẹsẹ̀ mi àti ìmọ́lẹ̀ sí ipa ọ̀nà mi.** **Bíbélì – Orin Dafidi 119 ẹsẹ 105**



# Orin Dafidi 23

***>> ọrọ ti a mọ daradara lati inu Bibeli <<***

***Oluwa li oluṣọ-agutan mi; Emi ki yio ṣe alaini***

***O mu mi dubulẹ ninu papa oko tutu. O mu mi lọ si iha omi didakẹ rọrọ.***

***O tu ọkan mi l'ara; O mu mi lọ si ọna ododo nitori orukọ Rẹ***

***Nitõtọ, bi emi tilẹ nrìn larin afonifoji ojiji ikú, emi kì yio bẹ̀ru ibi; nitori iwọ wà pẹlu mi; Ọpá Rẹ àti ọ̀gọ Rẹ, nwọ́n ntù mí nínú.***

***Iwọ pese tabili silẹ niwaju mi niwaju awọn ọta mi; O fi òróró kun orí mi; ago mi sí kún àkúnwọsílẹ.***

***Nitotọ ire ati aanu yio máa tọ mi lẹhin ni gbogbo ọjọ aiye mi; èmi yiò sì máa gbé ni ile Oluwa laelae.***

ORIN DAFIDI

**Saamu yi wa fún gbogbo eniyan. Nje ohunkohun ha dara ju ati ni anfani lati sọ pe: "Oluwa ni oluṣọ-agutan mi?"**

**Ni awọn akoko aini, paapaa nigbati o ba dojukọ iku, o le ri itunu tootọ: "Bẹẹni, bi mo tilẹ nrin l'aarin afonifoji ojiji iku.... Iwọ wa pẹlu mi."**

# Ẹri to dara julọ

Ní ọjà, olùtajà èso kan wà lẹ́hìn ilé ìtajà rẹ̀. Nígbà tí kò sí oníbààrà, ó máa ńlo gbogbo ìgbà láti ka Bíbélì rẹ̀, ìwé tó ṣe iyebíye l'ójú rẹ̀.

"Iwe wo ni o máa nka yẹn?" onibara rẹ gbogbo ìgbà bere. **"Bibeli mi, Ọrọ Ọlọrun."** "O dara" bawo ni o ṣe mọ pe eyi ni Ọrọ Ọlọrun? Tani sọ fun ọ?" "Ọlọrun tikararẹ." "Ah, ṣe Ọlorun tikararẹ ba ọ sọrọ ni?" ọkunrin naa beere pẹlu ẹgan.

Obìnrin na ko mọ ohun ti yíò sọ fún ìgbà díẹ̀ 'torí pé kò mọ bó ṣe lè fi hàn **pé Bíbélì jẹ́ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.** Ṣugbọn lẹhinna o tọka si oorun didan o sọ fún olubara rẹ: "Ṣe o le fi múlẹ̀ pe eyi ni oorun?" ki nfi han ọ?" o dahun. **"Iyẹn rọrun. Ẹri ti o dara julọ ni pe o fun mi ni imọlẹ ati ooru."**

"Bẹẹ gann ni", obinrin na dahun. **"Iyẹn jẹ ẹri ti o dara julọ pe iwe yii jẹ Ọrọ Ọlọrun: o fun mi ni imọlẹ ati imaraya ninu."**





# Bibeli Dindin

Jan Hus ni a le pe ni alatunṣe ati ajeriku ti Bohemia. Nípasẹ̀ ẹ̀rí tí ó wà láàyè, ojú ẹgbẹẹgbẹ̀rún ni a ṣí sí iṣẹ́ ìràpadà tí a ti parí nípasẹ̀ Jesu Kristi.

Ṣugbọn ikede ihinrere ti gbangba yi ko pẹ ni orilẹ-ede yi. Nwọ́n dá iná sun Jan Hus l'órí òpó igi, ẹ̀jẹ̀ àwọn Kristẹni miran sì ńṣàn lọ́pọ̀lọpọ̀, nwọ́n sì ńwá Bíbélì kiri láti ba wọ́n jẹ́.



Láàárín àkókò yí, obìnrin kan, tí ìṣúra rẹ̀ tó ga jù lọ jẹ́ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run, dúró níwájú ààrò rẹ̀ láti ṣe búrẹ́dì. Lojiji o gbọ pé àwọn ọkùnrin ti nṣe inúnibíni nlọ kiri ilu lati mu ẹnikẹni ti nwọn ba ri pẹlu Bíbélì.

Ó yára gbé Bíbélì rẹ̀, ó sì dì í sínú ìyẹ̀fun ńlá kan, ó sì tì í sínú ààrò, o sì kó àwọn búrẹ́dì iyókù sí ẹ̀hìn rẹ̀ gan-an.

Laipẹ lẹhinna, a tun wa ile rẹ pẹlu. Nwọn yẹ ohun gbogbo wo, lati igun kan dé aja, ṣugbọn lasan ni.

Lẹ́hìn tí àwọn tó ńṣe inúnibíni náà ti kúrò ní ilé rẹ, nwọ́n ṣe búrẹ́dì náà, nwọ́n sì gbé e jáde nínú ààrò. Sì wò ó, kíyèsí i, ìwọ̀nba díẹ̀ ni Bíbélì ti o bà jẹ́ bí àwọn ọkùnrin mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ni, Ṣádírákì, Méṣákì àti Àbẹ́dínígò, tí a sọ sínú iná ìléru. Bíbélì jẹ́ ká mọ bí Ọlọ́run ṣe mú wọn jáde kúrò nínú ìléru láìfarapa.
Bíbélì – Dáníẹ́lì 3.

**Oluwa Ọlọrun mi, iwọ li emi gbẹkẹle; gbà mí lọ́wọ́ gbogbo àwọn tí ńṣe inúnibíni sí mi; si gbà mi.**
Bíbélì – Orin Dafidi 7 ẹsẹ 1

# Oju akọmalu

**“Bibeli kii ṣe fun mi,” Peteru sọ fun ọrẹ rẹ, “nitori pe ọpọlọpọ ni a kọ si inu rẹ ti emi ko l’oye.”**

**Ken ronu fun igba diẹ. Ó mọ̀ dáadáa pé Pétérù kàn fẹ́ wá àwáwí ni. Ni ana ni o ti ji nkan ninu agbala aladugbo rẹ. Nitori naa Ken dahun pe: “Ohun kan ni a kọ sinu Bibeli ti o le mọ dajudaju.” “O dara, kini?” “Iwọ ko gbọdọ jale!”**

**Ìyẹn dà bí ọfà kan tó gún Pétérù l’ọ́kàn. O ronu ti ọjọ ti o kọja, o sì rọra rin kuro.**

## Ẹniti o li àiyà arekereke kì yio ri ire, ati ẹniti o li ahọn arekereke ṣubu sinu ibi.

Bíbélì – Òwe 17 ẹsẹ 20

# Bíbélì Tí A Sọnu

Nígbà tí nwọ́n ńlọ sí ilé ní òpin ọ̀sẹ̀, ọ̀pọ̀ àwọn ọmọ ogun ńrìnrìn àjò papọ̀ tí nwọ́n sì ńṣere l’ọ́nà pẹ̀lú ara wọn.

Ọ̀dọ́ ọmọ ogun kan jóko sí ẹ̀gbẹ́ ọ̀nà ọkọ̀ ojú irin, ó ńka Bíbélì àpò rẹ̀. Lojiji, ọmọ-ogun miran dide, o sọ pe: “Jẹ ki a gbadun diẹ pẹlu rẹ.” Lẹ́hìn tó ti sọ bẹ́ẹ̀, ó gba Bíbélì l’ọ́wọ́ ọ̀dọ́mọkùnrin náà, ó sì jùú si ita lati ojú fèrèsé.

Gbogbo eyi ṣẹlẹ ni iṣẹju aaya, Bibeli na si bọ sí ojú irin. Njẹ ọdọmọkunrin jagunjagun naa fo dide ni ibinu bi? Rárá o, ó rántí ọ̀rọ̀ Jésù Olúwa pé: **“Mo jẹ́ oninu tutu àti onírẹ̀lẹ̀ ní ọkàn”** (Mátíù 11:29). O banujẹ, ṣugbọn o dakẹ.

**Ọ̀sẹ̀ díẹ̀ lẹ́hìn náà,** ọ̀dọ́ ọmọ ogun yií gba ẹ̀bùn kan pẹ̀lú Bíbélì rẹ̀ nínú rẹ̀. lẹta kan ti o dùn sí wa ninu rẹ. Òṣìṣẹ́ ọkọ̀ ojú irin kan, tó ńṣiṣẹ́ l’órí ọ̀nà náà, ti rí Bíbélì. Nígbà tí ó ṣí i, tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí nkàa, Ọlọrun sọ̀rọ̀ sí ọkàn rẹ̀. Titi di igba naa o ni iberu nla nitori ẹri-ọkan ti o jẹbi, ṣugbọn nipasẹ kika Bibeli , o ri idariji awọn ẹṣẹ rẹ nipa gbigbagbọ ninu iṣẹ irapada Jesu Oluwa. Lẹ́hìn náà, sójà náà l’óye ìdí tó fi ní láti wà láìsí Bíbélì rẹ̀ fún ọ̀sẹ̀ mélò kan. Ọlọ́run ní àwọn ọ̀nà àgbàyanu láti dé ọkàn àwọn ènìyàn, Èṣù, ọ̀tá ńlá Ọlọ́run, tún ba ijakulẹ pade.

## Ìwọ ti pinnu ibi sí mi; ṣugbọn Ọlọrun pinnu rẹ fun rere…

**Bíbélì – Genesisi 50 ẹsẹ 20**



# Bíbélì Tí O Ya

Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́hìn, lilu awọn nkan ilé kan ta wà ní ìlú kékeré kan. Lára wọn ni Bíbélì àtijọ́ ńlá kan, ṣugbọn kò si éni tó nífẹ sí i. Nikẹhin, onişowo kan ṣe ipese ati pe o ni anfani lati mu lọ si ile fun iwọn owo diẹ.



Onisowo ti o ni ero ti iṣe wipe ki o fi awọn oju-ewe rẹ wé awọn ọja ti o nta. ko ronu nipa iyebiye nla ti oju-ewe ti iwe yi ni. Ọlọ́run ti sọ pé: **"[Ọ̀rọ̀ mi] kì yiò padà s'ọ́dọ̀ mi lásán"** (Aísáyà 55 ẹsẹ 11).

Ní ìlú yìí, ni ọkùnrin kan tún ńgbé, ẹni tí wọ́n ńfì iyà jẹ nígbà gbogbo nítorí èrò pé òun jẹ̀bi ikú ẹnìkan. Ko ri isimi l'ọsan tabi ni oru. Ọrọ naa "apaniyan" duro nigbagbogbo niwaju oju rẹ ni awọn lẹta didan. Ni ọjọ kan o ran ọmọ rẹ ni ile itaja yẹn lati ra nkan kan. Ọmọkunrin naa pada wa ohun elo ti a beere ti a we sinu apakan ti Bibeli atijọ yi. Lojiji ni ẹsẹ yi lati inu Heberu 9 ẹsẹ 22 wá sí oju ọkunrin yi pe: **"Laisi itajẹsilẹ ko si idariji."**



Ni akọkọ, awọn ọrọ wọnyi ko ni itunmọ̀ fun u. Sibẹ o nwa idariji. O ni lati mọ sii nipa rẹ ni gbogbo ọna. Nítorí náà, ó tún rán ọmọkùnrin rẹ̀ lọ sí ọ̀dọ̀ oníṣòwò náà, ẹnití ó ti bẹ̀rẹ̀ sí nya àwọn ojú-ewé láti inú Episteli kini ti Johannu. Nígbà tí ọkùnrin yi tí nwọ́n ńdá lóró nípa ẹ̀bi rẹ̀ ká oju ewe na, gbogbo ẹrù náà sọkalẹ kuro ni ọkàn rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ nitoriti ó kàa pé **"Ẹ̀jẹ̀ Jésù Kristi Ọmọ Rẹ̀ ńwẹ̀ wá mọ́ kúrò nínú ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo" àti "Bí a bá jẹ́wọ́ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa, Olóòótọ́ àti olódodo ni Oun láti dárí àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá àti láti wẹ̀ wá mọ́ kúrò nínú àìṣòdodo gbogbo"** (1 Jòhánù 1:7 & 9).

Awọn ọrọ wọnyi tàn bi imọlẹ sinu ọkan okunkun rẹ. Ó ní ìrírí pé ẹ̀jẹ̀ Jésù Kírísítì Olúwa, tí Ó ta sílẹ̀ ní orí àgbélébù, lè wẹ gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ nù. Nipasẹ eyi, gbogbo eniyan ti o jẹwọ ẹṣẹ wọn fun Ọlọrun le ri alafia pipe fun ọkan ati ẹri-ọkan wọn.

Ọrọ Ọlọrun ti di ibukun fun awọn miliọnu eniyan. Ni ọpọ igba o le jẹ ẹsẹ kan tabi oju-iwe kan lati inu Bibeli. Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run "yè, ó sì lágbára, ó sì ńgún ni" (Hébérù 4:12). Bayi ni Ọlọ́run ṣe "mì" ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọkàn líle tàbí ti o ti bà jẹ́.

Paapaa Bibeli ti o ya le ṣamọna eniyan si ọna ayọ gidi...

## Òtítọ́ Ni Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run

Òtítọ́ ni Ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Ó máa ń̄kan ẹnì kọ̀ọ̀kan nínú ẹ̀rí ọkàn nwọn, ó máa ńfi ibi tí nwọ́n ti ṣe àṣìṣe hàn wọ́n, ó sì máa ńjẹ́ kí wọ́n ní aibàlẹ̀ ọkàn àti ìdààmú. Eyi mu ki ọpọlọpọ eniyan bẹru Bibeli ati nitori bẹẹ , awọn miran ti gbiyanju lati paa rẹ.

## Ọrọ Ọlọrun Wà Titi lae

Ṣùgbọ́n Ọlọ́run ńṣọ́ Ọ̀rọ̀ Rẹ̀, kì yio sì kọja lọ láé.

**Ko gbogbo awọn iwe ti o sọrọ l'odi si Bibeli sori ara wọn, ati pe iwọ yio ni opo kan ti o ga ju okiti giga Giza lọ. Lẹ̀hìn náà, fi Bíbélì lélẹ̀ lẹ́gbẹ òkìtì yi. Bibeli pe perepere. O jẹ aṣẹgun, O sì wà láàyè rékọjá gbogbo awọn ti o wà l'odi sii.**





**Ṣugbọn ọrọ Oluwa duro laelae.**

Bíbélì - 1 Pétérù 1 ẹsẹ 25

**Titi Láé, Oluwa ọrọ Rẹ kalẹ ni ọrun.**

Bíbélì - Orin Dafidi 119 ẹsẹ 89

**Òtítọ ni gbogbo ọ̀rọ̀ Rẹ, gbogbo ìdájọ́ òdodo Rẹ sì wà títí lae.**

Bíbélì - Orin Dafidi 119 ẹsẹ 160



# Bibeli dabi...

## Akara

Eyi ni onjẹ ti o ti ọrun sọkalẹ wá, ki enia ki o le jẹ ninu rẹ̀, ki o má si kú.
Jòhánù 6 ẹsẹ 50



## Ina



Ọ̀rọ̀ mi kò ha dàbí iná? li Oluwa wi.
Jerimáyà 23 ẹsẹ 29

## Imọlẹ

Ọ̀rọ̀ rẹ ni fìtílà fún ẹsẹ̀ mi àti ìmọ́lẹ̀ sí ipa ọ̀nà mi. Orin Dáfídì 119 ẹsẹ 105



## Wara



Gẹ́gẹ́ bí ọmọ tuntun, ẹ máa fẹ́ wàrà mímọ́ ti ọ̀rọ̀ náà, kí ẹ lè dàgbà nípa rẹ̀.
1 Pétérù 2 ẹsẹ 2

## Oyin

O dun pelu ju oyin ati oyin igan.
Orin Dafidi 19 ẹsẹ 10






## Wura

Nwọ́n wu ni ju wúrà lọ, àní ju ọpọlọpọ wúrà dáradára lọ. Orin Dafidi 19 ẹsẹ 10



## Fadaka



Ọ̀rọ̀ OLUWA ni ọ̀rọ̀ mímọ́, bí fadaka tí a dán wò ninu iná ìléru, tí a sọ di mímọ́ nígbà meje. Orin Dafidi 12 ẹsẹ 6.

## Dingi

Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run jẹ́... onímọ̀ ìrònú àti ète ọkàn. Kò sì sí ẹ̀dá tó pamọ́ lójú Rẹ̀. Heberu 4 ẹsẹ 12 àti 13



## Oolu



Ọrọ mi ko ha dabi òòlù irin ti nfọ́ apata túútúú? Jerimáyà 23 ẹsẹ 29

## Ida

Idà Ẹ̀mí, èyí tí nṣe ọ̀rọ̀ Ọlọ́run.
Éfésù 6 ẹsẹ 17 àti Hébérù 4 ẹsẹ 12



## Irúgbìn náà



Aidibajẹ [irugbin]... ọrọ Ọlọrun ti o wa laaye ti o si duro laelae.
1 Pétérù 1 ẹsẹ 23

# Awọn imọran fun Kika Bibeli

**Ka Bibeli lati ni ibapade taara pẹlu Ọlọrun. O le bẹrẹ, fun apẹrẹ, pẹlu Ihinrere Luku ninu Majẹmu Titun, akọọlẹ kan ti igbesi aiye Jesu Kristi. Síwájú sí i, Májẹ̀mú Titun jẹ́ kọ́kọ́rọ́ láti l'óye Májẹ̀mú Láéláé.**

**Ti o ba fẹ ka Bibeli pẹlu ayọ ati ere, awọn ipele meje wọnyi jẹ iranlọwọ:**

## 1. Lo itumọ ti o dara

> Lo Bibeli ti o rọrun lati ye ni, ṣugbọn ti o jẹ apẹrẹ ti o sunmọ ti ọrọ ipilẹṣẹ.

(O ṣe ni laanu, awọn ẹda Bibeli wa ninu eyiti ẹniyan le ri Iyapa kuro ninu ojúlówó ẹkọ inú Bibeli)

## 2. Wa akoko

> Pinnu lati fi idamẹrin wakati kan silẹ ni gbogbo ọjọ fun "akoko idakẹjẹ" lati pade Ọlọrun.

Ọjọ kan ni idamẹrin wakati mẹrin din ni ọgọrun: fi ọkan ninu wọn fun Ọlọrun. O fẹ lati ba ọ sọrọ.

## 3. O nilo idakẹjẹ

> Ka Bibeli ni ibi idakẹjẹ.

Nitootọ, o le ka Bibeli l'ori aiyelujara, tabi ṣe igbasilẹ rẹ sí orí fóònù rẹ. Ṣùgbọ́n bí o bá ńka Bíbélì lati inu ìwé, ipínyà ọkan rẹ yio dínkù, iwọ yio sì lè p'ọ̀kàn pọ̀ dáadáa.

## 4. Gba Adura sí Ọlọrun

> Beere lọwọ Ọlọrun lati ran ọ lọwọ lati l'oye ohun ti o ti ka.

Kò s'ẹ́ni tó lè ṣàlàyé Bíbélì ju ẹni tó kọ ọ́ lọ.

> Beere lọwọ Ọlọrun: "Kini o fẹ sọ fun mi? Bawo ni mo ṣe le fi si iṣe?"

Oun nikan ni yio rii sinu ọkan rẹ ati pe O tun mọ awọn inira ati ohun ti ọ yi ọ ká.

> Dupẹ lọwọ Ọlọrun fun Ọrọ Rẹ iyebiye.

Kika Bibeli nmu ibukun ati ere nla wa. Wo Orin Dafidi 119 -162

## 5. Ṣe àṣàrò nípa rẹ̀

> Ronú nípa ohun tí o ti kà.

Kò wúlò tí o bá ńka Bíbélì ní kánjúkánjú. Wo Orin Dafidi 119 ẹsẹ 15&27&48

> Ṣe afihan awọn ọrọ pataki ati akiyesi awọn ọrọ ti o jọ ara wọn.

Iwọ yio ni anfani lati ri wọn pẹlu irọrun nigba miran, iwọ yio si ranti wọn daada si.

## 6. Kọ ẹkọ nipa ọkàn

> Fi ọkàn kọ ẹkọ awọn ẹsẹ ti o ti ṣe pataki si ọ.

Iwọ yio le ṣe iranti wọn nigbakugba. Nitorinaa wọn yio jẹ iranlọwọ fún ọ ni awọn ọna pupọ ni igbesi aiye. Wo Orin Dafidi 119 ẹsẹ 11, Kólósè 3 ẹsẹ 16

## 7. Fii si iṣe

> Ṣe ohun ti Ọlọrun fihan ọ ati sọ fun ọ ninu Bibeli.

Ìgbọràn sí Ọlọ́run máa ńmú inú rẹ dùn ó sì máa mú kí àjọṣe Rẹ pẹ̀lú rẹ̀ jinlẹ̀ sí i. Wo Jakọbu 1 ẹsẹ 22 .

**Alabukún-fun li awọn ti o gbọ́ ọrọ Ọlọrun ti nwọn si pa a mọ́.**

**Bíbélì – Luku 11:28**

# A nilo ipinnu!

O ti gba ọpọlọpọ awọn imọran ati ọpọlọpọ alaye nipa Bibeli, "lẹta" lati ọdọ Ọlọrun si ọ. Jọwọ fun Ọlọrun ni idahun ni bayi. Maṣe taàri ipinnu naa kuro! Ó yẹ ki o mọ̀ pé ó ṣe pàtàkì gan-an láti fetí sí Ọlọ́run. Boya o ko ni ni aaye miran.

Ọlọrun fẹ lati tọọ wa ni aanu ati ore-ọfẹ kii si nṣe bi onidajọ. O pe ọ lati yipada si Oun. Ṣugbọn ti o ba tẹsiwaju pẹlu aibikita ti o si kọ ifiranṣẹ Ọlọrun, a jẹ wipe ọna rẹ nlọ si ipinya aiyeraiye kuro l'ọdọ Ọlọrun, eyiti o jẹ ọrun apadi.

**Ṣugbọn Ọlọrun ṣe ipese iyanu fun ọ nipasẹ Ọmọ Rẹ̀, Jesu Kristi:**

**Ninu adura si Ọlọrun, o le ni itunu kuro ninu gbogbo awọn ẹṣẹ rẹ pẹlu awọn ọrọ ti o rọrun ati otitọ. Inú Rẹ dùn láti dáríjì ọ nígbà tí o bá fi wọ́n hàn an. Sọ fun u pe o ti gbe laisi Rẹ̀ ati pe o ti ṣẹ sii. Ti o ba ṣe eyi nitootọ, o le gbagbọ nitõtọ pe Jesu Kristi ti san gbese fun awọn ẹṣẹ rẹ nigbati o lọ sinu iku l'ori agbelebu.**

**Ti o ba gba ẹbun nla yii ni igbagbọ, ọna si ọrun yio ṣi fun ọ, ibi idapọ ayọ aiyeraiye pẹlu Ọlọrun. Lẹhinna igbesi aiye rẹ yio ni itumọ ati ìpinnu rere.**

Ọlọrun ni inu didun nla si ọ. Nítorí náà, O ńbá ọ sọ̀rọ̀ nípasẹ̀ lẹ́tà Rẹ̀, Bíbélì. O fẹ kí iwọ ni igbala ati lati gba alaafia tòótọ. Ó nífẹ̀ẹ́ rẹ gan-an O sì bìkítà nípa rẹ.

Jọwọ ka Bibeli lai boju w'ẹhin ati pẹlu ọkan-iṣipaya. Da Ọlọrun lohun! Dupẹ lọwọ Rẹ ninu adura pe Ọrọ rere Rẹ̀ ti de ọdọ rẹ, ati pe o ti gbaa. Ìyẹn yiò jẹ́ ayọ̀ ńlá fún Ọlọ́run!

**Ayọ̀ yio pọ̀ sí i ní ọ̀run lórí ẹlẹ́ṣẹ̀ kan tí ó ronúpìwàdà.**

Bíbélì – Luku 15 ẹsẹ 7



Ayọ nla ni yio jẹ fun ọ ti o ba le sọ fun Ọlọrun pe:

**Mo jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ mi fún ọ, bẹ́ẹ̀ ni nkò sì fi ẹ̀ṣẹ̀ mi pamọ́. Mo wí pé, "Èmi yiò jẹ́wọ́ ìrékọjá mi fún Olúwa," ìwọ sì ti dárí àìṣedédé ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí.**

**Bíbélì - Orin Dafidi 32 ẹsẹ 5**

Nígbà náà àwọn ìlérí Ọlọ́run tó fẹsẹ̀ múlẹ̀ titi láé yíò kan ìwọ náà:

**... Mo fun wọn ni iye ainipẹkun, nwọn ki yio ṣegbe lae; bẽ̃ni ẹnikan kì yio gbà wọn li ọwọ́ mi.**

**Bíbélì – Jòhánù 10 ẹsẹ 28**

**Kiyesi i, emi wà pẹlu nyin nigbagbogbo, ani titi de opin aiye.** **Bíbélì – Mátíù 28 ẹsẹ 20**



## Contact addresses in Nigeria

**Echoes of Truth Literature**
Km 16, Ojodu-Ijoko Road, Nepascoop Estate Bus Stop,
Olajumoke Akute, Ogun State, Nigeria.
Phone: +234 8033064183, 8023514002
Email: echoes_of_truth@yahoo.com

**The Hope of Glory Believers Bookstore**
33, Kayode Street, Onipanu, Lagos State Nigeria.
Phone: +234 8028752390
Email: believersbookstore@yahoo.co.uk

**Timelesstruth Christian Publications & Outreach**
The Bible Centre, 19 Bishop Hughes Avenue,
Off College Road, Cinema Bus Stop, Ogba-Ikeja, Lagos Nigeria.
Phone: +234 7088805357, 8023030696, 8137161295
Email: timelesstruth23@gmail.com

**Word of Truth**
S13 Aliyu Makama Road, Barnawa Kaduna.
Phone: +234 8033714705
Email: daveofasanya@yahoo.com

**Christian Literature & Help Service**
P.O. Box 436 Ijeshatedo Surulere, Lagos Nigeria.
Phone: +234 8033359655
Email: clahs.org@gmail.com

publisher:

GBV

**GBV Dillenburg GmbH**
www.gbv-dillenburg.de
www.gbv-online.org

ISBN 978-3-98824-165-8

GBV 199 4010 A Letter for You Yoruba